# IWA ONIGBAGBỌ́ -- NINU ILE ATI LAAARIN IJỌ

**Efesu 6:1-4**

**ẸKỌ 356 -- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin ninu Oluwa: nitoripe eyi li o tọ́" (Efesu 6:1).**

### Igbọran si awọn obi

"Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin." Eyi ti jẹ ohun inira fun awọn ọmọde lati ṣe tó! Wọn a maa wa ọ̀na lati máṣe ohun ti awọn obi wọn fẹ nipa ṣiṣe oriṣiriṣi awawi. Ọna ti ara wọn ni wọn sa n fẹ. Ni ọ̀pọlọpọ igba ni wọn maa n rò pe awọn gbọ́n ju awọn obi wọn lọ, ati pe awọn obi wọn ti di ẹni igbà atijọ.

Ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun ni: "Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin ninu Oluwa, nitoripe eyi li o tọ́," "Ninu Oluwa." Bi awọn obi rẹ ba fẹ ki o ṣe ohun ti o lodi si eyi ti Jesu n fẹ́, o lẹtọọ lati kọ̀ fun wọn. Ṣugbọn o gbọdọ gbọ́ ti awọn obi ti n ṣe ohun ti o tọ́.

"Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ; (eyi ti iṣe ofin ikini pẹlu ileri), ki o le dara fun ọ, ati ki iwọ ki o le wà pẹ li aiye" (Efesu 6:2, 3).

### Awọn Ọmọde ti o Layọ

Ọlọrun mọ ohun ti i mu inu eniyan dùn, O si n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ layọ. Awọn ọmọde ti i maa ṣe ifẹ inu-ara wọn ki i layọ. Awọn wọnni ti a jẹ niya nigba ti wọn wà ni èwe, ti wọn si mọ̀ bi a ti i gbọran si awọn obi wọn lẹnu ati bi a ti i huwa rere si gbogbo eniyan laini ẹmi imọ-ti-ara-ẹni-nikan, a maa layọ ju awọn wọnni ti wọn fẹran lati maa ṣe ohun ti o wù wọn. Njẹ o rò pe ọmọ ti o n binu nitori ki o le ṣe ohun ti o fẹ́ le ni ayọ̀?

Wo bi yoo ti jẹ ohun inira fun awọn ẹni ti o ni ọmọ olóri kunkun, alaigbọran ati onikanra lọdọ. Sọlomọni wi pe: "Ọlọgbọ́n ọmọ ṣe inu-didùn baba rẹ̀, ṣugbọn aṣiwere ọmọ ni ibanujẹ iya rẹ̀" (Owe 10:1). Ọlogbọ́n ọmọ ni ẹni ti o gbọran si Ọrọ Ọlọrun ati ti o n bọ̀wọ fun awọn obi rẹ̀. Aṣiwere ọmọ ni ẹni ti o n ṣaigbọran si Ọlọrun ati eniyan.

Ọlọrun n ṣọ́ ohun gbogbo ti a n ṣe. O n ṣọ́ awọn ọmọde, O si ti rán angẹli oluṣọ lati daabo bo wọn; ṣugbọn bi wọn ba taku sinu iwa iṣọtẹ wọn, a nilati jẹ wọn niya. Wọn yoo jiya ninu aye yii; bi wọn kò ba si ronupiwada, wọn yoo tun jẹ iya ti o pọju bẹẹ nigba ti wọn ba duro niwaju Onidajọ gbogbo ayé.

Awọn obi gbọdọ kọ́ awọn ọmọde bi a ti ṣe le jẹ olugbọran. A kò bi iwa rere mọ́ awọn ọmode. Wolii Isaiah ni: "Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan" (Isaiah 53:6); Onipsalmu wi pe: "Nwọn ti ṣina lojukanna ti a ti bi wọn" (Orin Dafidi 58:3). A gbọdọ kọ́ awọn ọmọde lati inu ile lati maa mọ̀ ọ fun ẹlomiran ati lati mọ̀ bi a ti i pa ofin mọ́. Awọn ti o ṣe alainaani aṣẹ awọn obi wọn kò ni le bọwọ fun ofin ilu, tabi ofin Ọlọrun.

Nigba ti Jesu paapaa Ẹni ti I ṣe Ọmọ Ọlọrun wa si ayé gẹgẹ bi eniyan, O n gbọran si awọn obi Rẹ̀ nipa ti ara lẹnu. O fi apẹẹrẹ bi a ṣe nilati gbé lelẹ fun wa. Awọn ọmọde miiran rò pe awọn ti dagba ju lati gbọ́ ti awọn obi wọn tabi ki a jẹ wọn niya, nigba ti wọn ba ti tó ọmọ ọdun mejila. Nigba ti Jesu di ọmọ ọdun mejila a ri I ninu Tẹmpili nibi ti O gbé n fi Bibeli bá awọn Ju ti i ṣe olukọni sọrọ. O sọ fun iya Rẹ̀ pe Oun kò le ṣaima wà nibi iṣẹ Baba Oun ti n bẹ ni ọrun, eyi ti o jẹ́ ohun pataki. Sibẹ O bá Maria ati Josẹfu pada lọ si Nasarẹti, "O si fi ara balẹ fun wọn" (Luku 2:51).

### Aṣẹ ti a pa fun awọn obi

Awọn obi yoo jihin fun Ọlọrun lori ọ̀na ti wọn gba tọ́ awọn ọmọ wọn. A paṣẹ fun awọn naa paapaa lati ọdọ Ọlorun pe: "Ati ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ nyin binu: ṣugbọn ẹ mã tọ́ wọn ninu ẹkọ́ ati ikilọ Oluwa" (Efesu 6:4). O jẹ́ ojuṣe awọn obi lati ri i pe awọn ọmọ wọn gbọran; ṣugbọn wọn gbọdọ jẹ oniyọ́nu, ki wọn si ba ni wi pẹlu ifẹ ninu ọkàn wọn.

Nigba ti Ọlọrun yan Abrahamu lati jẹ́ baba orilẹ-ède Ju, O ri iwa pataki kan ninu rẹ̀ ti yoo jẹ iranwọ́ lati fi ipilẹ orilẹ-ède naa lelẹ. O wi pe: "Nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o ma pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ; ki OLUWA ki o le mu ohun ti o ti sọ fun Abrahamu wá fun u" (Gẹnẹsisi 18:19).

Awọn ọmọ Onigbagbọ́ yoo jẹ́ iranlọwọ fun awọn obi wọn lọpọlọpọ bi wọn ba n le bá awọn obi wọn kọ́ ẹ̀kọ́ papọ̀ ninu Bibeli pẹlu ifọwọ sowọpọ̀ lati gbọran si Ọrọ naa. Awọn ọmọ ati awọn ọmọ-ọmọ Abrahamu ràn án lọwọ lati mú ifẹ Ọlọrun ṣẹ nipa gbigbọran si ohun ti o ba sọ ati si awọn aṣẹ Ọlọrun.

**Didara pọ̀ mọ́ ayé**

Nigba gbogbo ni awọn ọmode maa n rò pe ohun ti o ṣe pataki julọ ni igba ọ̀dọ́ wọn ni lati ni ẹ̀kọ́ ti o yanjú, lati dabi awọn ọ̀dọ́ ẹlẹgbẹ wọn ti wọn ju mọ n lọ si ile-ẹ̀kọ́ papọ̀. Ẹgbẹ́ jọdá aṣọ yoo jẹ ohun gunmọ́ pẹlu. Ẹgbẹ ayé, ere idaraya, ile-ijo, ati ode-apejẹ maa n tan ọ̀pọlọpọ ọ̀dọ́ kuro ninu Ọrọ Ọlọrun. Wọn ni ifẹ ati di olokiki laaarin awujọ eniyan, ni igba pupọ awọn obi wọn maa n gbiyanju lati ṣe iranwọ fun wọn. Ọpọlọpọ iya ni o maa n lo aṣọ ti kò nilaari ki wọn ba le ri owo lati fi dá aṣọ ti o ba òde mu fun awọn ọmọbinrin wọn. Awọn obi yoo du ara wọn ni ọ̀pọlọpọ nnkan ki wọn ba le fun awọn ọmọ wọǹ ni anfaani pupọ ninu ayé.

Ṣugbọn ki ni anfaani ti o tobi julọ ninu ayé? Bi awọn obi wa kò tilẹ fi ohunkohun silẹ fun wa ninu awọn ohun rere ayé yii, bi wọn ba fi apẹẹrẹ igbesi-ayé Onigbagbọ́ ati igbẹkẹle tootọ ati igbagbọ́ ninu Ọrọ Ọlọrun lelẹ fun wa, kò si ogún ti o tobi ju eyi lọ. Aye yii pẹlu ọlá ati igberaga rẹ̀ yoo kọja lọ laipẹ. Ṣugbọn ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa yoo wà titi.

**Pẹpẹ Adura Agbo-ile**

"Agboolé ti o ba jọ n gbadura papọ̀ yoo wà papọ̀," jẹ́ gbolohun ti a maa n saba tọka si. A kò le ri idapọ ti o gbadun nibikibi ju ibi pẹpẹ adura agbo-ile ati ajumọ kọ ẹ̀kọ́ papọ̀ ninu Bibeli. Ọlọrun bukun ẹsin agbo-ile nitori ti o jẹ́ igbọran si ifẹ Ọlọrun. Aṣẹ Ọlọrun lati ẹnu Mose ni: "Ki ẹnyin ki o si ma fi wọn (awọn ọ̀rọ Ọlọrun) kọ́ awọn ọmọ nyin, ki ẹnyin ma fi wọn ṣe ọ̀rọ isọ nigbati iwọ ba joko ninu ile rẹ, ati nigbati iwọ ba nrìn li ọ̀na, nigbati iwọ ba dubulẹ, ati nigbati iwọ ba dide" (Deuteronomi 11:19). Ṣugbọn kikọ́ Ọrọ Ọlọrun ninu ile kò tó. A gbọdọ mu awọn ọmọde lọ si Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi ati Ile-isin. Awọn ọmọ kéékèèké a maa kọ́ ẹ̀kọ́ pupọ ninu isin awọǹ agba, ibukun Ọlọrun a si maa wà lori wọn.

Nigba ti Jọṣua n fun awọǹ Ọmọ Israẹli li aṣẹ, awọn ọmọ wẹẹrẹ wọn wà nibẹ pẹlu. "Kò kù ọ̀rọ kan ninu gbogbo eyiti Mose palaṣẹ, ti Jọṣua kò kà niwaju gbogbo ijọ Israẹli, ati awọn obirin, ati awọn ọmọ wẹrẹ ati awọn alejò ti nrin lãrin wọn" (Jọṣua 8:35). Wò bi ayọ̀ wọn ti pọ to nigba ti Ọlọrun tú ibukun Rẹ̀ sori ẹbọ wọn! "Nitori Ọlọrun ti mu wọn yọ̀ ayọ̀ nla, aya wọn ati awọn ọmọde yọ̀ pẹlu, tobẽ ti a si gbọ́ ayọ̀ Jerusalẹmu li okere reré" (Nehemiah 12:43).

Jesu n fẹ́ awọn ọmọde ninu isin Rẹ̀. O wi pe, "Ẹ jẹ ki awọn ọmọ kekere ki o wá sọdọ mi, ẹ má si ṣe da wọn lẹkun: nitoriti irú wọn ni ijọba Ọlorun" (Marku 10:14). Bi awọn ọmọde ba jẹ pataki fun Jesu bayii, ro bi o ti tọ́ ki wọn ṣe huwa nigba ti wọn ba wà ni ile Ọlọrun. O fẹran wọn O si n fẹ wọn nibẹ; ṣugbọn wọn gbọdọ fi ọlá ati ọ̀wọ fun ile Rẹ̀. Wọn gbọdọ dakẹ jẹ́ ki wọn si duro jẹ́ lai rin kiri nigba ti ẹnikan ba n ṣiwaju gbogbo ijọ ninu adura. Ọlọrun ni o n bá sọ̀rọ, awọn naa nilati gbadura pẹlu.

Ni akoko kan awọn alufaa buburu n fẹ́ mú Jesu, nigba ti ọ̀pọ ninu awọn eniyan ti kuro ninu Tẹmpili. Ṣugbọn ọ̀pọ awọn ọmọde ti wọn fẹran Jesu, wà ninu Tẹmpili, wọn si n kọrin wi pe, "Hosanna fun Ọmọ Dafidi." Eyi bí awọn alufaa ninu, ṣugbọn Jesu wi pe: Ẹnyin kò ti kà a ninu iwe pe, Lati ẹnu awọn ọmọ-àgbo ati awọn ọmọ-ọmu ni iwọ ti mu iyin pé?" (Matteu 21:15, 16). Awọn ọmọde wọnyii bu ọlá fun Jesu ju awọn agba ti wọn jẹ́ ẹlesin lọ.

Ni igba pupọ ni awọn ọmọde Onigbagbọ́ tootọ ti mu awọn obi wọn mọ Jesu. Ọmọde kekere le ri igbala ninu Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi, ki o si lọ sọ fun awon obi rẹ̀ nipa ayọ̀ ti o ni ninu ọkàn rẹ̀. O si ti gbadura fun awọn obi rẹ̀. Ọlọrun maa n gbọ́ adura ti ọmọde kekere ba gbà pẹlu igbagbọ́, A si maa dahun. Ni ọ̀pọlọpọ igba ni awọn ẹlẹṣẹ maa n tẹ́ eti silẹ lati gbọ́ Itan Jesu lati ẹnu ọmọde nigba ti wọn kò ni ṣuja ohun ti agbalagba n sọ. Wo bi ihuwasi ọmọde ti ṣe pataki tó! Ati ohun nla ti igbesi-ayé ti o n gbé fun Jesu le ṣe!

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ofin Ọlọrun fun awọn ọmọde?

2 Ki ni ileri Rẹ̀ fun igbọran?

3 Awọn ọmọde wo ni o layọ̀?

4 Nibo ni a gbé nilati kọ́ kọ́ ọmọde bi a ti i pa ofin ati aṣẹ mọ́?

5 Bawo ni a ṣe mọ̀ pe Jesu gbọran si awọn obi Rẹ̀ lẹnu?

6 Ki ni ofin Ọlọrun fun awọn obi?

7 Ki ni awọn ohun ti o wà ni ile-ẹ̀kọ́ ti o le ṣi ọkàn ọmọde kuro lọdọ Ọlọrun bi oun kò ba ṣọra?

8 Ki ni ogún wa ti o tobi julọ ninu ayé yii?

9 Ki ni Jesu sọ nipa titẹwọgba awọn ọmọde?

10 Ki ni awọn ohun ti ọmọde onigbagbọ́ le ṣe fun awọn obi wọn?